ÌPÍNLẸ̀ PENNSYLVANIA

# ATỌ́NÀ OLÙDÌBÒ SÍ ÌDÌBÒ ỌDÚN 2024

5 Oṣù-kọkànlá Ọdún 2022

## ILÉ AṢÒFIN ÀGBÀ ORÍLẸ̀-ÈDÈ U.S.

Ìgbìmọ̀, tí ń ṣe ẹ̀ka aṣòfin ìjọba àpapọ̀, ní àwọn ilé méjì: Ilé Aṣòfin Àgbà Orílẹ̀-èdè U.S. àti Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin Orílẹ̀-èdè U.S. Ìbò tí ó pọ̀ jùlọ ní ilé méjèjì yẹ láti fọwọ́ sí òfin ìjọba àpapọ̀. Ìdá 60% ìbò tó pọ̀ jùlọ nílò ní Ilé Aṣòfin Àgbà láti gba ọ̀pọ̀ àbádòfin wọlé.

Wọ́n ma ń yan àwọn ọmọ aṣòfin àgbà ní gbogbo ọdún 6, àti pé àwọn Aṣòfin Àgbà 100 ni wọ́n wà ní Ilé Aṣòfin Àgbà, níbití ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan ti ní àwọn Aṣòfin tí wọ́n ń ṣojú wọn. Igbákejì Ààrẹ Orílẹ̀-èdè U.S. ni adarí Ilé Aṣòfin Àgbà Orílẹ̀-èdè U.S. ó sì lè jẹ́ gẹ́gẹ́ bí àlékún ìbò nígbà tí ilé bá pín. Ilé Aṣòfin Àgbà nìkan ní agbára láti fidí àwọn ìyànsípò Ààrẹ múlẹ̀ bíi àwọn Adájọ́ Ilé-ẹjọ́ tó Ga Jùlọ àti àwọn Ipò Ìgbìmọ̀ Aṣèjọba.

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

Òfin láti Ilé Aṣòfin Àgbà dá lórí àwọn ọ̀rọ̀ bíi ètò ìlera, àtúnṣe ìdájọ́ ìwà ọ̀daràn, ìwọlé-wọ̀de èrò, àti ohun amáyédẹrùn COVID-19. Ìyapa ẹnu ní Ilé Aṣòfin Àgbà ma ń fa ìdíwọ́ fún ìjókòó-ṣòfin pàtàkì.

## ALÁYẸ̀WÒ ÌWÉ OWÓ

Aláyẹ̀wò Ìwé Owó Àgbà fún Ìpínlẹ̀ Pennsylvania ń kó ipa pàtàkì láti rii pé ètò ìnáwó ìpínlẹ̀ náà kó àkóyawọ̀. Èyí pẹ̀lú iyẹ̀wé-owó-wò láti rii dájú pé owó àwọn tí wọ́n ń san owó-orí jẹ́ lílò ní ọ̀nà tó dára, ṣíṣe ìgbéléwọ̀n bí àwọn ètò ìjọba ṣe ṣiṣẹ́ sí, àti ṣíṣe ìgbéláruge fún ìwà gbangba-làṣá-ta àti ìtẹ̀lé àwọn òfin àti àlàkalẹ̀. Nípa ìtọ́ka sí àwọn ibi tó nílò ìmúdára àti ṣíṣe àwọn àkànṣe ìwádìí, Aláyẹ̀wò Ìwé Owó Àgbà ń dá sí ìṣàkóso àwọn ohun àmúlò ìpínlẹ̀ ní ọ̀nà tó dára.

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

Ojúṣe Aláyẹ̀wò Ìwé Owó Àgbà ní ìpínlẹ̀ Pennsylvania ṣe pàtàkì bí ó ti ṣe ń rii dájú pé wọ́n ń pín àwọn ohun àmúlò bó ṣe yẹ àti ìwà gbangba-làṣá-ta. Nípasẹ̀ yíyẹ ìwé owó wò yẹ́bẹ́-yẹ́bẹ́, Aláyẹ̀wò Ìwé Owó Àgbà ń ṣiṣẹ́ láti ṣàwárí àwọn àìṣe-déédé, mú ìgbéláruge bá níná owó ní ìwọ̀tún-wọ̀nsì, àti láti dásí fífi òpin sí àwọn ìdíwọ́ nínú ìjọba, tí ó sì ń mú ìgbòòrò bá ìpínlẹ̀ tí ó ń fi ti gbogbo ènìyàn ṣe.

## AGBẸJỌ́RÒ ÀGBÀ FÚN ÌJỌBA

Agbẹjọ́rò Àgbà fún Ìjọba Ìpínlẹ̀ Pennsylvania jẹ́ amòfin àgbà fún ìpínlẹ̀ náà, tí ó ń gba Gómìnà àti àwọn àjọ ìjọba ní ìmọ̀ràn nípa òfin, ó ń pe àwọn ẹjọ́ tako ìwà ọ̀daràn tí ó ṣe pàtàkì sí ìpínlẹ̀, ṣíṣe àmúṣẹ àwọn òfin ààbò olùrajà, pípè fún àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, ṣíṣe àmójútó ìtẹ̀lé òfin, àti ṣíṣe iṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn agbófinró. Ojúṣe náà ṣe pàtàkì sí fífi ìdí òfin múlẹ̀ ní Ìpínlẹ̀ Pennsylvania.

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

**Ní báyìí o ti ní gbogbo àlàyé tí o nílò láti fi dìbò.**
**Kọ́ ẹ̀kọ́ sii nípa àwọn olùdíje tí wọ́n ń du ipò ní àdúgbò rẹ níbí:**
**VOTE411.ORG/BALLOT**

**O ti ṣetán láti kó ipa tìrẹ. O ní gbogbo** àlàyé tí o nílò láti fi dìbò. Fún àlàyé nípa ilé ìdìbò rẹ tàbí láti fi àwọn ẹjọ́ tó níiṣe pẹ̀lú ìdìbò sùn, pe: 866-OUR-VOTE

Ojúṣe Agbẹjọ́rò Àgbà ní ìpínlẹ̀ Pennsylvania ṣe pàtàkì fún àwọn àwùjọ wa bó ti ṣe ń ṣe ìgbéláruge fún fífi ìdí àwọn òfin múlẹ̀ ní ìwọ̀ntún-ìwọ̀nsì àti ìdáàbò bo àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn. Agbẹjọ́rò Àgbà ń kó ipa pàtàkì láti wá ojútùú sí àwọn ọ̀rọ̀ tó níiṣe pẹ̀lú àlàkalẹ̀ ìjọba, gbígbógun ti ìdẹ́yẹsí, àti àrídájú orí-ò-ju-orí lábẹ́ òfin. Nípa ṣíṣe àwọn ẹjọ́ ẹlẹ́yàmẹ̀yà, pípè fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àtúntò ìdájọ́ ìwà ọ̀daràn, àti ìdáàbò bo àwọn ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, Agbẹjọ́rò Àgbà ń dásí ìmúgbòòrò àwùjọ tí ó ní ìdájọ́ òdodo tí ó sì ń fi ti gbogbo ènìyàn ṣe ní ìpínlẹ̀ Pennsylvania.

## ILÉ ÌGBÌMỌ̀ AṢOJÚ-ṢÒFIN ORÍLẸ̀-ÈDÈ U.S.

Ìgbìmọ̀, tí ń ṣe ẹ̀ka aṣòfin ìjọba àpapọ̀, ní àwọn ilé méjì: Ilé Aṣòfin Àgbà Orílẹ̀-èdè U.S. àti Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin Orílẹ̀-èdè U.S. Ìbò tí ó pọ̀ jùlọ ní ilé méjèèjì yẹ láti f'ọwọ́ sí òfin ìjọba àpapọ̀. Gbogbo ọdún 2 ni wọ́n ma ń yan àwọn Aṣojú-ṣòfin. Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-sòfin lè ṣe àgbéjáde àwọn àbádòfin owó-orí.

Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin Orílẹ̀-èdè U.S. náà ní àwọn ọmọ aṣòfin 435 tí wọ́n ń tún pín ní gbogbo ọdún 10 lẹ́yìn Ìkànìyàn.

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

Òfin láti Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin náà dá lórí àwọn ọ̀rọ̀ bíi ètò ìlera, àtúnṣe ìdájọ́ ìwà ọ̀daràn, ìwọlé-wọ̀de èrò, àti ohun amáyédẹrùn COVID-19. Ìyapa ẹnu ní Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin náà ma ń fa ìdíwọ́ fún ìjókòó-ṣòfin pàtàkì.

## AṢÒFIN ÀGBÀ ÀTI ỌMỌ AṢOJÚ-ṢÒFIN ÌPÍNLẸ̀ PA

Ní ìpínlẹ̀ Pennsylvania, ẹ̀ka ìjọba tó ń ṣe òfin pín sí ọ̀nà méjì: Ilé Aṣòfin Àgbà àti Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin. Ìbò tí ó pọ̀ jùlọ ní ilé méjèèjì yẹ láti f'ọwọ́ sí òfin ìjọba ìpínlẹ̀.

Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin àti Ilé Aṣòfin Àgbà ní agbára kan náà láti ṣe òfin, ṣùgbọ́n Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin nìkan ló lè ṣe àgbéjáde àwọn àbádòfin owó-orí, tí Ilé Aṣòfin Àgbà nìkan sì ní agbára láti fìdí àwọn ìyànsípò tí Gómìnà dábàá múlẹ̀, tó fi mọ́ àwọn ipò ìgbìmọ̀ aṣèjọba, àwọn ìgbìmọ ilé-ẹ̀kọ́ fásitì ìpínlẹ̀, àti àwọn àyè tó bá ṣí sílẹ̀ ní ẹ̀ka ìdájọ́.

Gbogbo ọdún 4 ni wọ́n ma ń yan àwọn Aṣòfin Àgbà, nígbà tí wọ́n ń yan àwọn Aṣojú-ṣòfin ní gbogbo ọdún 2.

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

Àwọn Aṣòfin Àgbà àti àwọn ọmọ Aṣojú-ṣòfin Ìpínlẹ̀ Pennsylvania ti ṣe òfin láti ná owó sí àwọn àǹfààní SNAP, ṣe àtúntò àwọn ọlọ́pàá, ná owó sí àwọn ilé-ẹ̀kọ́, kí wọ́n sì fún àwọn agbègbè ní owó láti ara owó-orí.

## ÀWỌN ÀTÚNṢE ÒFIN

Ilé Aṣòfin Ìpínlẹ̀ Pennsylvania lè dábàá àwọn ọ̀nà ìgbàdìbò fún ìbò. Òfin Ìpínlẹ̀ Pennsylvania nílò ìbò tó pọ̀ jù (50%+1) ní ìgbìmọ̀ kọ̀ọ̀kan (Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣojú-ṣòfin Ìpínlẹ̀ àti Ilé Aṣòfin Àgbà Ìpínlẹ̀) ní ìjókòó-ṣòfin méjì léra wọn lójúná àti fi àwọn Àtúnṣe Òfin kún ìwé ìdìbò. Àwọn Àtúnṣe Òfin tó gba iwájú ilé aṣòfin kọjá tó wá hàn lórí ìwé ìdìbò gẹ́gẹ́ bíi àwọn àlàkalẹ̀ ìbò tí àwọn olùdìbò dìbò láti f'ọwọ́ sí tàbí kọ̀.

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

Àwọn àtúnṣe kò nílò ìbuwọ́lù Gómìnà láti fi ránṣẹ́ sí ibi ìbò tàbí di òfin tí wọ́n bá f'ọwọ́ síi. Èyí lè mú kí àwọn àlàkalẹ̀ ìbò jẹ́ ọ̀nà láti fo àyẹ̀wò àti ìwọ̀ntún-wọ̀nsì tó wà láàrin ẹ̀ka aṣòfin àti ẹ̀ka aṣèjọba ìpínlẹ̀ náà.

**Ní báyìí o ti ní gbogbo àlàyé tí o nílò láti fi dìbò.**
**Kọ́ ẹ̀kọ́ síi nípa àwọn olùdíje tí wọ́n ń du ipò ní àdúgbò rẹ níbí:**
**VOTE411.ORG/BALLOT**

**O ti ṣetán láti kó ipa tìrẹ. O ní gbogbo** àlàyé tí o nílò láti fi dìbò. Fún àlàyé nípa ilé ìdìbò rẹ tàbí láti fi àwọn ẹjọ́ tó níiṣe pẹ̀lú ìdìbò sùn, pe:
866-OUR-VOTE

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

Igbákejì Gómìnà yó di Gómìnà tó bá ṣẹlẹ̀ pé Gómìnà tó wà níbẹ̀ lọ́wọ́ kò ríbi ṣe ìjọba mọ́. Gẹ́gẹ́ bíi Alága Ìgbìmọ̀ tó ń rí sí Ìtúsílẹ̀ àwọn Ẹlẹ́wọ̀n, ní àìpẹ́ ọdún a ti rí bí ojúṣe yìí ṣe jẹ́ pàtàkì sí fún àtúntò ìwà ọ̀daràn. Igbákejì Gómìnà lè ṣe kí Ìgbìmọ̀ tó ń rí sí ọ̀rọ̀ Ìtúsílẹ̀ àwọn Ẹlẹ́wọ̀n tú àwọn ènìyàn sílẹ̀, tó fi mọ́ àwọn tí wọ́n ń ṣe ẹ̀wọ̀n fún egbògi olóró igbó, kí wọ́n rí ìtúsílẹ̀ kúrò ní ẹ̀wọ̀n.

## Akápò

Ojúṣe akápò ìpínlẹ̀ Pennsylvania ni láti mójútó owó ìpínlẹ̀ náà, láti mójútó àwọn oko-òwò, gbèsè, àti ìwọlé-wọ̀de owó. Wọ́n jẹ́ gẹ́gẹ́ bíi alákóso owó ìlú, wọ́n ń ṣe ojúṣe ìfowópamọ́, tí wọ́n sì ń jábọ̀ ìnáwó láì sí ìrújú. Akápò ń kó ipa pàtàkì láti ríi dájú pé wọ́n ń ná owó ìlú bó ṣe tọ́ tí wọ́n sì tún le ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nípa ìnáwó àtì àwọn ètò ìgbaniníyànjú.

### KÍNI ÌDÍ TÍ Ó FI ṢE PÀTÀKÌ?

Ipò Akápò ní ìpínlẹ̀ Pennsylvania ṣe pàtàkì fún àwọn agbègbè, láti ríi dájú pé àwọn ètò ìnáwó àti pínpín ohun àmúlò lọ ní ìwọ̀ntún-wọ̀nsì bó ṣe tọ́. Nípasẹ̀ àkóso àti ìgbaniníyànjú ìnáwó tí kò rújú, Akápò ń dá sí wíwá ojútùú sí àwọn àìṣedéédé létò ọrọ̀-ajé àti ṣíṣe ìgbéláruge fún ẹ̀kọ́ ìnáwó, mímú ìmúgbòòrò bá ètò ọrọ̀-ajé tó fi ti gbogbo olùgbé ṣe.

## O ti ṣetán láti kó ipa tìrẹ. O ní gbogbo

àlàyé tí o nílò láti fi dìbò. Fún àlàyé nípa ilé ìdìbò rẹ tàbí láti fi àwọn ẹjọ́ tó níiṣe pẹ̀lú ìdìbò sùn, pe:

866-OUR-VOTE

**ÈDÈ SPANISH: 888-VE-Y-VOTA (1-888-839-8682)**

**ÈDÈ LÁRÚBÁWÁ: 844-YALLA-US (1-844-925-5287)**

**ÀWỌN ÈDÈ ILẸ̀ ASIA: 888-API-VOTE (1-888-274-8683)**

**ÌPÈ ONÍFÍDÍÒ ÈDÈ ADITÍ ILẸ̀ AMẸ́RÍKÀ: 301-818-VOTE (8683)**

## Ní báyìí o ti ní gbogbo àlàyé tí o nílò láti fi dìbò.

Kọ́ ẹ̀kọ́ síi nípa àwọn olùdíje tí wọ́n ń du ipò ní àdúgbò rẹ níbí:

**VOTE411.ORG/BALLOT**

